VIRGINIA DEPARTMENT OF SOCIAL SERVICES

VIRGINIA SUN BUCKS

# Kinni Virginia SUN Bucks?



Virginia SUN Bucks máa nṣe ìrànlọ́wọ́ fún àwọn ìdílé tí wọ́n ní àmúyẹ pẹ̀lú owó onjẹ ní àkókò isinmi sáà ooru ní àkókò tí èyí tí ó pọ̀ jùlọ nínú àwọn ilé-ìwé wà lẹ́nu isinmi. A lè fi ànfàànì SUN Bucks ra onjẹ bí èso tuntun, ẹ̀fọ́, àwọn onjẹ oníwóró tí èròjà wọn pé, wàrà, àti ẹran ní àwọn ilé ìtajà onjẹ, ọjà àwọn àgbẹ̀ àti àwọn ibi tí wọ́n ti ntẹ́wọ́ gba àwọn ànfàànì SNAP EBT.



Ọmọ kọ̀ọ̀kan tí ojú orí rẹ̀ bá ti ilé-ìwé mu tí ó kún ojú ìwọ̀n ètò náà yóò gba

**owó sísan onígbà kan ti $120**

## Àwọn Ànfàànì

A ó fi àwọn ànfàànì sórí káàdì EBT àwọn olùgbà SNAP tó wà nílẹ̀ nígbà tí àwọn yòókù yóò gba káàdì Virginia SUN Bucks tuntun nínú àpótí ìfiwéránṣẹ́.






## Ìròyìn Ayọ̀!

Ìròyìn ayọ̀ náà ní pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìdílé ni ó yẹ fún Virginia SUN Bucks tẹ́lẹ̀ wọn kò sì níí nílò láti gbé ìgbésẹ̀ kankan láti gba ànfàànì tuntun yìí!

### Tani ó ye fún Virginia SUN Bucks tẹ́lẹ̀ tí kò sì nílò láti béèrè fún u?

**A ti fi orúkọ ọmọ rẹ sílẹ̀ sínú Virginia SUN Bucks tẹ́lẹ̀ bí ó bá:**

- Ngba àwọn ànfàànì**Ètò Ìrànlọ́wọ́ Àfikún Onjẹ** (SNAP) tàbí**Ìránlọ́wọ́ Onígbà Díẹ̀ fún Àwọn Ìdílé Aláìní** (TANF) tàbí nkópa nínú Medicaid tí ó dá lórí owó ọ̀yà.
- Ti béèrè fún ó sì ti gba onjẹ ọ̀fẹ́ tàbí ẹlẹ́dìnwó ní ilé-ìwé ní àkókò **odún ẹ̀kọ́ 2025-2026** nípasẹ̀ Ètò Ọnjẹ Ọ̀sán Ilé-ìwé Gbogbogbò.

### Báwo ni màá ṣe mọ̀ bóyá ìdílé mi nílò láti béèrè fún Virginia SUN Bucks?

**O gbọ́dọ̀ béèrè fún Virginia SUN Bucks bí ọmọ rẹ kò bá béèrè fún** tí ó sì gba onjẹ ilé-ìwé ọ̀fẹ́ tàbí ẹlẹ́dìnwó tí ìdílé rẹ kò sì kópa nínú SNAP, TANF tàbí Medicaid tí ó dá lórí owó ọ̀yà. **Àwọn ilé-ìwé kan máa npèsè oúnjẹ ọ̀fẹ́ fún àwọn ọmọ láì béèrè.** Bí ọmọ rẹ bá ń lọ sí ọ̀kan nínú àwọn ilé-ìwé yìí tí kò sì máa kópa nínú SNAP, TANF tàbí Medicaid tí ó dá lórí owó ọ̀yà, ó yẹ kí o béèrè!

## Àwọn déètì pàtàkì

| | |
|---|---|
| **Ó wà lẹ́nu iṣẹ́ yípo ọdún** | **Àwọn bíbéèrè fún lórí ẹ̀rọ àti ti ìfiwéránṣẹ́ ti yọjú lórí VirginiaSunBucks.com** |
| **Ọjọ́ 15 Oṣù Kẹfà Ọdún - Ọjọ́ 31 Oṣù Kejọ Ọdún** | **Ibùdó Ìpè Virginia SUN Bucks wà ní àrọ́wọ́tó fún àwọn ìbéèrè orí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀** |
| **Ọjọ́ 31 Oṣù Kejọ Ọdún** | **Ọjọ́ t́ ó kẹ́yìn láti béèrè lórí ẹ̀rọ, nípa ìfiwéránṣẹ́ tàbí pípe ibùdó ìpè** |